# ÀYẸ̀WÒ ÌWÚLÒ TÍỌ́RÌ Ẹ̀YÌN ODI FÚN ÌTÚPALẸ̀ LÍTÍRÉṢỌ̀ YORÙBÁ

**TÁYÉ FATIMA SHEU**

**Department of Nigerian Languages,**

**Kwara State College of Arabic and Islamic Legal Studies,**

**Ìlọrin, Kwara State**

**Ìfáárà**

Tíọ́rì ni irinṣẹ́ tí oníṣẹ́ lítíréṣọ̀ máa ń lò láti fi ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ kan. Àwọn òyìnbó ni wọ́n gbé tíọ́rì yìí kalẹ̀, kó tó di wí pé àwọn aláwọ̀ dúdú náà wá gùnlé tíọ́rì wọ̀nyí láti fi ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ wọn. Ṣíṣe àmúlò tíọ́rì òkè òkun yìí mú kí àwọn oníṣẹ́ lítíréṣọ̀ wa ilẹ̀ délẹ̀ lórí àtúpalẹ̀ tí wọ́n fẹ́ ṣe. Nínú iṣẹ́ yìí, á wo ohun tí tíọ́rì fúnra rẹ̀ gan-an jẹ́, á sì ṣe àlàyé lórí bí tíọ́rì òkè òkun ṣe wúlò nínú àtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀.

**Kí ni Tíọ́rì?**

Ọbáfẹ́mi (1997) kí tíọ́rì báyìí, ó ní:

> Theory is the aesthetic of discourse improving disciplines, to achieve a harmony between the artist’s vision, knowledge of craft and successful communication.

Èyí túmọ̀ sí pé:

> Tíọ́rì ni irinṣẹ́ ìmọ̀ nípa ẹwà lítíréṣọ̀ láti jẹ́ kí ìbáṣepọ̀ ó wà láàárin ìran òǹkọ̀wé, ìmọ̀ọ̀nse rẹ̀ àti ìbánisọ̀rọ̀ tó péye.

Bákan náà ni Lérè Adéyẹmí náà sọ nínú ìwé pé: “Tíọ́rì dàbí abẹ́fẹ́lẹ́ ìmọ̀ tí a fi ń la ìfun àti ẹ̀dọ̀ iṣẹ́ kan”. Ó yẹ kó yé wa pé gbogbo ìwádìí yòówù tí kò bá gùnlé tíọ́rì kan pàtó nínú iṣẹ́ ìwádìí sáyẹ́ǹsì òfútùfẹ́tẹ̀ ni.

Onírúurú tíọ́rì lítíréṣọ̀ ló wà tí àwọn oníṣẹ́ ọnà máa gùnlé nígbà tí wọ́n bá fẹ́ ṣe ìtúpalẹ̀. Àwọn tíọ́rì náà ni.

1. Tíọ́rì ìfojú ààtò wò
2. Tíọ́rì ìfojú ìhun wò
3. Tíọ́rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀
4. Tíọ́rì ìṣègbèfábo
5. Tíọ́rì Asàtakò ìmúnisìn
6. Tíọ́rì Asàtakò ọ̀làjú
7. Tíọ́rì Ajẹmọ́làjú
8. Tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò
9. Tíọ́rì ìfojú-ìtàn-ìgbésí-ayé-òǹkọ̀wé-wò
10. Tíọ́rì Ajẹmọ́-ìmọ̀-ìtàn
11. Tíọ́rì ìfojú-inú-wò
12. Tíọ́rì ìfojú-iṣẹ́-ọkàn-wò
13. Tíọ́rì ìfojú-ìhun-tío-so-pọ̀-mọ́-ìsẹ̀lẹ̀-àwùjọ-wò.

**ÌWÚLÒ TÍỌ́RÌ Ẹ̀YÌN ODI FÚN ÌTÚPALẸ̀ LÍTÍRÉṢỌ̀ YORÙBÁ**

Gẹ́gẹ́ bí ati ṣe máa wí pé gbogbo tíọ́rì tí a dárúkọ yìí, kì í ṣe tíọ́rì tí àwa aláwọ̀ dúdú dá sílẹ̀ bí kò ṣe, láti òkè òkun ní gbogbo àwọn tíọ́rì náà tí hù jáde kó tó di wí pé ó tàn dé ilẹ̀ aláwọ̀ dúdú. Tíọ́rì yìí ni a lè fi ṣe àlàyé nǹkan tàbí fi ṣe òdiwọ̀n lórí ohun tí òǹkọ̀wé kọ jáde. Tí a bá wò ó á rí i wí pé gbogbo tíọ́rì yìí ló wúlò fún ṣíṣe àtúpalẹ̀ àwọn ìwé eré Onítàn, Eré-Oníṣe, Ewì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

1. Tíọ́rì Marx tó ṣe àtakò fún ètò ìrẹ́nijẹ, tíọ́rì yìí wúlò nítorí pé, ó lòdì sí ìwà ìrẹ́nijẹ tó ń wáyé ní àwùjọ wa, bí àpẹẹrẹ nínú ìwé *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọládẹ̀jọ Òkédìjí kọ, á rí i wí pé Láwúwo ń jà fún ẹ̀tọ́ àwọn òṣìṣẹ́ tó wà ní abẹ́ rẹ̀, Láwúwo rí i wí pé àwọn agbaniṣiṣẹ́ ń rẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ jẹ. Ó jà láti rí i wí pé ohun gba ẹ̀tọ́ àwọn òṣìṣẹ́ tí ó ń ṣe olórí lé lórí fún wọn. Síbẹ̀ síbẹ̀ lára àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ rẹ̀ (Ìdòwú) náà ni wọ́n lò fún Láwúwo láti dá ojú rẹ̀ bolẹ̀, láti mú un kó jáwó, lórí ohun tí ó ń jà lé lórí, gbogbo

akitiyan Láwúwo pàbó ló jású. Tíọ́rì Marx yìí wúlò púpọ̀ torí pé ó tako gbogbo ohun tó jẹ mọ́ ìmúnisìn, àwọn tó gbé tíọ́rì yìí kalẹ̀ gbà pé àparò kan kò ga jù kan lọ. Pé kò yẹ kí àwọn kan wà ní ipò ọlá, kí wọ́n máa wá rẹ́ àwọn ọmọ ẹ̀yìn wọn jẹ.

2. Tíọ́rì wúlò púpọ̀ torí ó jẹ́ kí á rí bí a ṣe ń bá ara wa gbé pọ̀ tàbí ṣe pọ̀ ní àwùjọ, tí a bá wo àwọn òǹkọ̀wé a rí i wí pé nínú àwùjọ ni òǹkọ̀wé ti jáde, gbogbo ohun tí òǹkọ̀wé sì fẹ́ lò inú àwùjọ ni wọ́n ti wá, bí i, ẹ̀dá ìtàn, kókó gan, akópa, èdè tí wọ́n a fi gbé e kalẹ̀ gan ohun ìní àwùjọ ni, nítorí náà la fi sọ wí pé àwùjọ ló bí òǹkọ̀wé, òǹkọ̀wé ló bí lítíréṣọ̀, àwọn nǹkan bí ìgbé ayé àwùjọ kò lè ṣe kó má farahàn nínú iṣẹ́ ọnà wọn. Ìdí yìí ni wọ́n fi ń ṣe àtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀. Tí a bá wo ìwé Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí ọ̀dẹ̀. Tí oníṣẹ́ lítíréṣọ̀ kò bá súnmọ́ àwùjọ, kí ló fẹ́ sọ lórí àwùjọ. Kò sì gbọdọ̀ sọ ohun tí ojú rẹ̀ kò tó sínú ìwé.

3. Tíọ́rì máa ń ṣe àgbéjinlẹ́ iṣẹ́ ọnà ju bí òǹkọ̀wé ṣe kàá sí lọ. Tí a bá wo àwọn ìwé tí D.O. Fágúnwà kọ, àwọn ìwé rẹ̀, Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmọlẹ̀, Àdìtú Olódùmarè, Igbó Irúnmọlẹ̀, a rí i wí pé gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ dá lórí inú igbó, iwin, òkè ńlá ńlá, odò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, Fágúnwà kúndùn inú igbó púpọ̀. Ní àkókò tí àwọn ìwé rẹ̀ yìí ń jáde, àwọn òǹkàwé fẹ́ràn ìwé rẹ̀ ní kíkà gan, ṣùgbọ́n nígbà tí ó di wí pé àwọn ìwé onítàn mìíràn ń jáde sórí àtẹ lọ́kan-ò-jọ̀kan ni àwọn onkawe bẹ̀rẹ̀ sí ní rí àlébù àwọn ìwé rẹ̀, nígbà tí wọ́n rí i wí pé àwọn òǹkọ̀wé yooku ń mú ẹnu ba ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ, wọ́n rí i wí pé Fágúnwà kò mẹ́nu ba ètò ọrọ̀ ajé nínú àwọn ìwé rẹ̀ tí ó kọ jáde kó tó di wí pé ó filẹ̀ sasọ bora. Síṣe àmúlò tíọ́rì ló jẹ́ kí wọ́n tanná rí ibi tí Fágúnwà kò mẹ́nu bà nínú ìwé rẹ̀.

4. Tíọ́rì tún ṣe àfihàn irú ẹni tí òǹkọ̀wé jẹ́ nínú ìwé tí wọ́n bá kọ. Nígbà tí a bá ṣe àmúlò tíọ́rì ìfojú ìtàn ìgbésí ayé òǹkọ̀wé ṣe ìtúpalẹ̀. A ní láti wádìí nípa ìtàn ìgbésí ayé òǹkọ̀wé, kí á rí ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà nínú iṣẹ́ ọnà òǹkọ̀wé. Tíọ́rì ìfojú ìtàn ìgbésí ayé òǹkọ̀wé yìí wúlò torí ó

máa jẹ́ kí ènìyàn mọ ohun tí ó mú u dágbálé ìwé kíkọ. Tí a bá wo ìwé “Ó le kú” Àjàní ni olú ẹ̀dá ìtàn, Àjàní sì ni oríkì Akínwùmí Ìṣọ̀lá, Ifáfitì Ìbàdàn ni Àjàní lọ, ó gboyè àkọ́kọ́ lórí èdè Faranṣé, tí a bá wo ẹ̀yìn ìwé “O le kú’ yìí á rí i wí pé àwọn mú ìdá dání tí Àjàní àti ìyàwó rẹ̀ sì kọjá labe rẹ̀, nígbà tí wọ́n ń ṣe ìgbéyàwó, èyí túmọ̀ sí wí pé Akínwùmí Ìṣọ̀lá jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ paireti nígbà tí ó wà ní Ifáfitì. Ìtàn ìgbésí ayé Akínwùmí Ìṣọ̀lá ni ó fi kọ ìwé rẹ̀ “O lé kú”. Nínú ìwádìí tí wọ́n ṣe pẹ̀lú rẹ̀ ni àwọn òǹkọ̀wé fi mọ̀ pé ìtàn ìgbésí ayé Ìṣọ̀lá ló kójọ papo fi kọ ìwé eré onítàn rẹ̀ “O lé kú”, bí kò bá sí tíọ́rì yìí kò sí ẹni tí o lè mọ àwọn ìtàn wọ̀nyí, bí wọn kò bá ṣe ìwádìí lọ sí ọ̀dọ̀ ohun gangan alára.

5. Síṣe àmúlò tíọ́rì jẹ́ kí àwọn obìnrin le jà fún ẹ̀tọ́ wọn nínú àwùjọ tí wọ́n bá bá ara wọn. Tíọ́rì ìṣègbèfábo ni tíọ́rì tí ó jáde lórí ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin nínú àwùjọ. Àwọn obìnrin aláwọ̀ funfun ni wọ́n díde wí pé àwọn ọkùnrin ń fi ọwọ́ rọ́ àwọn sẹ́yìn, wọ́n sì fi ẹ̀hónú wọn hàn lórí àwọn òfin tí ìjọba wọn gbé kalẹ̀ lórí àwọn obìnrin bii kí obìnrin mọ́ dìbò, bí obìnrin àti ọkùnrin bá jọ wà níbi iṣẹ́ ọkùnrin yóò máa gba owó ju obìnrin lọ. Ìdí niyi tí àwọn tó gbé tíọ́rì yìí kalẹ̀ ṣe bẹnu àtẹ́ lu àwọn tó ń fi ojú tínrín wo obìnrin ní àwùjọ. Ohun tí àwọn obìnrin wọ̀nyí ṣe láti mú kí èrò wọn gbilẹ̀ ni, wọn bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ ìwé lọ́kan-ò-jọ̀kan, wọ́n síṣe akitiyan láti rí i wí pé wọn fi òpin sí ìjẹgàba ọkùnrin lórí obìnrin. Tí a bá wo ilẹ̀ adúláwọ̀ a rí i wí pé ìse àwọn aláwọ̀ funfun yàtọ̀ sí ti aláwọ̀ dúdú. Ṣùgbọ́n bí ó ṣe jẹ́ wí pé tíọ́rì atọ̀húnrìnwá ni, a ti rí àwọn òǹkọ̀wébìnrin ni ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ní ilẹ̀ aláwọ̀ dúdú tí wọ́n sì ń ta ko àwọn òfin wọ̀nyí wí pé obìnrin kò gbọdọ̀ gbégbá fún ipò kankan. Àwọn òǹkọ̀wébìnrin wọ̀nyí ń kọ ìwé láti fi ṣègbèfábo, wọ́n ń ṣe àfihàn wí pé kò sí ohun tí ọkùnrin ṣe ti obìnrin kò le ṣe.

Tẹ́lẹ̀ àwọn òǹkọ̀wékùnrin ni wọ́n ń kọ ìwé lórí obìnrin. A rí Akínwùmí Ìṣọ̀lá gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé tó kọ Ẹfúnṣetán Aníwúrà, “Tinubu” orí àwọn obìnrin alákíkanjú ni òǹkọ̀wé náà kọ ìwé lé lórí. Nínú Ẹfúnṣetán Aníwúrà òǹkọ̀wé náà gbé ẹ̀wù ìkà wọ Ẹfúnṣetán, ṣùgbọ́n nídà keji

ó jẹ́ kí á rí i bí i alágbára obìnrin, kò bímọ, ó jẹ́ ẹni tí ó ń pàṣẹ, ṣé bó bá ṣe wu oníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ ló ṣe lè dámi rẹ̀ kaná. Iṣẹ́ ìtako obìnrin ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá ṣe níbí. Ìdí sì niyi tí aown ẹbí Ẹfúnṣetán Aníwúrà fi pe Akínwùmí Ìṣọ̀lá lẹ́jọ́, nígbà tí ó gbé ẹ̀wù burúkú wọ olú ẹ̀dá ìtàn rẹ̀, èyí ló sì ṣe okùnfà kíkọ ìwé rẹ̀ “Tinubu”. Àwọn tó gbé tíọ́rì yìí kalẹ̀ lo gbogbo agbára láti tọ́ wọn sọ́nà lórí ohun tó yẹ kan ṣe, kán sì yi ìwà padà lórí ohun tí wọ́n gbé lọ́kàn tẹ́lẹ̀.

6. Tíọ́rì máa ṣe ìrànlọ́wọ́ nínú síse ìtúpalẹ̀ àwọn ìwé, ó máa jẹ́ kí òǹkọ̀wé rí ìmọ̀ tuntun kọ́ nínú iṣẹ́ lámèyítọ́, wọ́n a máa fún ni lọ́gbọ́n tí èèyàn fi lè kọ̀wé tó bóde mu, ó sì máa ń ran òǹkọ̀wé lọ́wọ́ láti ní àtinúdá tó ga sí i.

7. Tíọ́rì wúlò fún àwọn òǹkàwé, lọ́pọ̀ ìgbà ni òǹkàwé yóò ka ìwé lítíréṣọ̀ tí kò ní ní ìmọ̀ tó kún. Òǹkọ̀wé lè kọ̀wé lọ́nà tí òǹkàwé yóò fi gbádùn ìtàn inú ìwé, èdè àti ìṣẹ̀lẹ̀ rẹ̀, ṣùgbọ́n kò ní rí ju ohun tó wà nínú ìwé lọ láìmọ̀ pé ohun tó wà lẹ́yìn ọ̀fà ju òje lọ. Iṣẹ́ lámèyítọ́ ni láti lo tíọ́rì tó yẹ láti fi tú àṣírí yìí sí òǹkàwé.

8. Lílo tíọ́rì láti fi ṣe àtúpalẹ̀ ìwé lítíréṣọ̀ ló jẹ́ kí ìwé lítíréṣọ̀ fi di mímọ̀ fún àwọn èrò àwùjọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwé Yorùbá tí ìbá ti di ìgbàgbé ló di mímọ̀ fún aráyé nípa síse ìtúpalẹ̀ wọn lédè Yorùbá, èdè Gẹ̀ẹ́sì àti èdè Faranṣé, nípaṣẹ̀ yìí òǹkọ̀wé gan-an á di mímọ̀ fún gbogbo ènìyàn.

**Àgbálọgbábọ̀**

Tíọ́rì wúlò púpọ̀ tí a bá fi ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀, ṣé òwe ni òǹkọ̀wé ń fiwé rẹ̀ pa, kì í lọ tààrà, iṣẹ́ lámèyítọ́ ni láti já koro yóówù tí òǹkọ̀wé bá dì, gbogbo ọ̀tẹ̀ tí lítíréṣọ̀ bá sì dì lámèyítọ́ ni yóò fi tíọ́rì tú u jáde. Ṣíṣe àmúlò tíọ́rì fún òǹkọ̀wé, òǹkàwé àti àwùjọ lápapọ̀.

**ÌWÉ TÍ A LÒ**

Adéyẹ́mí, L. (2000). *Tíọ́rì fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀*.

Fágúnwà, D.O. (1938). *Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmọlẹ̀.* Lagos: Nelson.

Fágúnwà, D.O. (1949). *Igbó Olódùmarè.* Lagos: Nelson.

Ìṣọ̀lá, A. (1970). *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Ìṣọ̀lá, A. (1974). *O lé kú*. Ìbàdàn: Uniersity Press.

Òkédìjí, O. (2009). *Rẹ́rẹ́ Run (Àtúnkọ).* Ìbàdàn: Extension Publication Limited Molete.